IDAJO IGA IDUNGANRAN DI OJO MERIN - ONI





# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO





VOL. No. IX 524. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JUNE 15, 1957. KOBO MEJI (2)



## Oba ilu Oyinbo ati awon Akeko meji

Awọn ọlọmọge meji ti • duro ti nwọn si ro aṣọ ilẹ Yoruba yi ni Omidan Fumilayọ Williams ọmọ Eko ati Omidan R. Ṣekoni ọmọ Ibadan.

Nwọn wa nisu ile ẹgbẹ ti British Council ki ọba obinrin ilu Oyinbo to de wa bẹ w ọ n w o nibẹ. Nigbati o ri awọn mejeji yi, o si ba wọn sọrọ pupọ.

Adọta-le-ni-ọdunrun ọmọ akẹkọ lo wa n i l e ẹgbẹ British Council lọjọ na, gbogbo wọn si wa lati ilu mẹrindilogun ninu awọn ilu ti o mbẹ labẹ aṣia Gẹsi, ṣugbọn aṣọ ilẹ Nigeria ati imura wọn l'o jọ ọba l'oju; nṣe ni awọn ilu yoku duro ti nwọn nworan.

## Idajo Iga Idunganran di ojo merin—oni

Oriṣiriṣi ni awọn irohin ti a ngbọ larapa ẹ j ọ Adeyinka ọmọ Oyekan ati Alaiyeluwa Adeniyi Adele Keji nilu Oyinbo, eyiti ọmọ Oyekan sọ wipe b a b a nla on Dosunmu lo ni Iga Ọba Eko. On si nfẹ gba ẹgbaa Pọun lọwọ ọba fun lile ti o le on jade k u r o ninu Iga Baba on.

Ẹnikini ti ro'jọ, Ọba Adele paapa si ro t i r ẹ wipe, Iga Idunganran jẹ ile ti gbogo ilu E k o k ọ nibiti awọn ọba Eko yio ma j'oye si. Latigba t i ilu Eko ti ṣẹ ni ọdun 1835, ibẹ ni awọn ọba Eko t i nj'oye si, ti nwọn si ngbe inu rẹ pẹlu.

Ẹjọ ti Adeyinka pe ni wipe, Dosunmu ti o nṣe baba-baba o n lo ni Iga Idunganran, ibẹ ni on si wa ti Adeniji Adele, Ọba Eko fi wa le on jade, nitorina ki Adajọ ba on gba ẹgbaa pọun lọwọ rẹ fun lile ti o le on jade, ki o si fi Iga na silẹ fun on.

Ẹjọ ti ọba si ro ni wipe Oloye Aromirẹ lo ni ilẹ, o si fi ta Babanla on lọrẹ wipe ki nwọn fi ibẹ kọ Afin nibiti gbogbo ọba Eko yio ma jẹ si. Ibẹ ni awọn ọba si ti njẹsi lati ọdun 1845. Ado jẹ, Gabaro jẹ; Akinṣemọyin jẹ, Idewu O j u l a r i, Adele k i n i, Oluwọle, Akintoye, Kosokọ bẹbẹ ki o to wa k a n Dosunmu. Ọna wo lo gba jẹ ti Dosunmu,

Bawo ni Dosunmu ti o ṣeṣẹ de ni ọsan gangan ṣe ni lati wa ni ile ti gbogbo ilu kọ. Lẹhin ti t'ọtun-t'osi wọn pari ẹjọ riro tan, awọn adajọ mẹta na wa fi ọjọ silẹ pe nigba ti o ba di ọjọ Atalata, 18th o ṣu June, ni awọn yio ṣe idajọ ọrọ yi. Adeyinka w a ni nibiti o gbe wa bẹni ọta Adele si nṣọla ninu Iga baba rẹ.

## Obinrin kan bi omo marun lekan

IKORODU. Obinrin kan ọmọ ogoji ọdun ni a gbọ wipe o bi ọmọ marun ni ikunlẹ kanṣoṣo, obinrin yi lati ọjọ ti o ti wọ ile ọkọ, ko loyun lati owurọ di alẹ ri.

Iyawo ti nwọn fẹ le e bi ọmọ mẹta, eyiti nwọn tun fẹ le, ti o ṣikẹta bi ọmọ meji, nwọn ko si fẹ ki iyale wọn ma ran ọmọ wọn nisẹ. Iyale wọn yi, o ṣe Kiriyo, o ṣe Imale, o ṣe Awo, o ṣe Oro nitori ki o le ri ọmọ bi; iro ni; pabo ni gbogbo rẹ.

Iyale yi ti su ọkọ rẹ; ko si tilẹ pe ran nisẹ mọ. Laifa ọrọ gun, Iyale na loyun ere ni, aṣaya ni, nṣe ni gbogbo awọn aladugbo nfi ṣe yẹyẹ wipe o loyun iju.

Bi ere, bi ere, obinrin na bi ọmọ marun ọkunrin mẹta, obinrin meji, gbogbo wọn lo si mbẹ ni alafia atiya at'ọmọ.

Ẹo ri oju aiye l'ode bi? Iṣẹ Ọlọrun, a wa maridi!

## [A]won ara Amerika je onje awon Angeli

AMERIKA Nile Amerika, ile kan wa ni ilu New York eyiti a ye ki a ma pe ni ile-iso Babeli l'e na ga tobe ge, bi ojo na ba su nwon fere le ma fi owo bu omi ni l'oju sanma giga ile na to ese 1,250 lati ori ile si oju sannmo. Nwon npe oruko ile iso na ni Empire State Building.

Loru ojo kan, ti ko si osupa ti oju orun si dudu, awon eiye nlala kan sigbo lati Iha Ariwa ile Amerika, nwon si nkoja lo iha Gusu. Bi nwon ti nfo lo, beni nwon nfi ori so ile iso giga yi, nwon si ja lule.

Nigbati ile mo, nse ni gbogbo awon aladugbo bere si se ase. Ha awon ara ile Amerika je onje awon angeli "Eiye ako" ni oruko awon eiye na.

## O[k]o Ofurufu beri O[k]imoto Kan

A gbo irohin wipe, oko ofurufu ti awon ara Amerika kan ti o nse idaraya loju sanma, gbogbera nibiti o gbe nra bale bo wa si ile, ki o to kanle, o yi biripe bi o ti tun nfe gbera lo si oke nse lo ge ori moto kan ti o wa ni iduro ni agbegbe ibe, o si ge ori Dereba moto na pelu, Derebati o wa oko ofurufu na fi ara sese pupo. Sugbon dereba yi ni nwon ntoju ti nwon si gbe lo sile alaisan nitoripe dereba moto ti ku, oko ofurufu na si jalule, o si jalule. o si baje pupo.

## Nilu Hausa, afoju bo Abere

KADUNA: Nijo ti mo ti nka kiri aiye nko ti ti ki afoju ma fi owu si abere ri! Eleti-Ofe ni on ri nkan ara ni Kaduna ti on lo ni lolo yi. Afoju aran aso o tun nfi owu sinu abere masinni. Eleyi sele nibiso ti ogbeni Oyinbo kan ti a npe ni Mr. E. CHAPMAN ti nko awon afoju nise orisirisi.

Onirohin Eleti-Ofe ni iyen nikan ko ni nkan ti on tun ri. Larin ibusun bi ogun, bi ogbon, onikaluku afoju lo mo ibiti on gbe osun ti o si mo ibiti kobodu ti on nfi nkan pamo si wa. O to eni mewa tabi mejila ti mo nso ninu won ti won ko mo wipe mo nso awon.

Oluko awon afoju yi, ogbeni E. Chapman, ni ko si nkan ti o le dun mo on lokan ju wipe, ki on ripe, on ran awon afoju lowo. O je mo wipe omo ogbeni yi papa wa ti o nse ise ofe (alaigba owo) larin awon afoju? Eleti Ofe ni on ti nbiti o gbe nse ise aselagun nibe.

## Awon Egbe W.H.O. Nile Afrika



BRAZZAVILLE Gege bi awon egbe alanu kan ti dide nisisiyi ti a npe ni Awon egbe ti o nwa alafia gbogbo agbaiye, ti nwon so wipe ile Afrika ni awon yio sise lodunni lati pano arun ete run nile na.

Awon ilu ti nwon o sise ni Gambia, Ghana, Nigeria nitoripe awon adete poju nilu nwonyi, Awon omo egbe ti a wi yi je ogedegede awon egbonkangi ninu ise isegun oyinbo ti nwon fi ara won jin lati sise na-

Ninu Aworan wa ose yi, ni a ri okan ninu awon Onisegun egbe W. H. O. ti o nse ayewo omo Hausa kan yala o ni arun ete lara tabi ko ni.

### Orin Begbaji

1. Oga l'o reru keru o
   Oga l'o r'eru ke'ru
   Oga l'o ra iya ab'opo-nidi
   Eru ti o ra yi ki nş'e eru re
   Padewa ! ş'on lo ma bi Padewa
   On ni'ya akapo oja
   Oga l'o reru ke'ru.
2. B'olowo ti nşe şaka-şaka Talaka nşe okan)
   Talaka ko je gari)
   Ko je gari o )
   Lalaifi nkan je )
   B'olowo ti nşe şaka-şaka,
   Talaka nşe okan


### IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamo ewa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ebin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

*(SILE MEJI ABO 2½d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS



### Kere o!

A ti ni orişirişi ogun German to şeşe de, fun oniruru aisan tokun-tokun. Tete wa ra tire k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.

# Awolowo De Ibi Mimo Ti John Wesley

ILU OYINBO. A ti ṣe ikede nipa irin ajo mimọ ti Oloye Awolọwọ rin lọ si ile Ologbe John Wesley ti o da isin ijọ Methodist silẹ.

Ninu ajọdun adọta-lerugba ọdun ti a bi Alufa Eni-ọwọ John Westley, eyiti nwọn ṣe nilu Oyinbo laipẹ yi, Oloye Awolọwọ jẹ ọkan ninu awọn enia ti o pejọ ṣe ajọdun na pẹlu wọn.

Ki nwọn to bẹrẹ isin na, olori awọn Alufa ti ijọ Wesley (Methodist) mu Awolọwọ Jin yika gbogbo ibi mimọ, ibiti a gbe bi John Wesley, iwe ti o nka, ibiti o njẹun, ati gbogbo ibiti o nlo si ni igba aiye rẹ. nwọn si tun yan odidi Alufa kan lati lọ fi iboji J. Westley han Oloye Awolọwọ ati iboji awọn enia nla nla ati awọn enia mimọ loju ọna ti ijọ Wesleyan (Methodist).

Ni gbogbo bi Oloye Awolọwọ ti nlọ kakiri ilu Oyinbo yi on pẹlu Oloye Okerodudu ni.

---

## Ero Gbohun-gbohun Nsise Olopa Ni Amerika

NEWYORK. Ninu ile ọja nla kan, lojojumọ ni awọn ọlọṣa ma nwa fọ ṣọbu na, awọn o si ko wọn lẹru lọ. Awọn ọlọpọ ṣọ ibẹ titi nwọn ko ri ẹnikan mu, bẹni nkan ko ye sọnu.

Nigbati o ṣe ni ọkanrin ọjọgbọn kan be wọn damẹran wipe ki nwọn lọ ra ẹrọ abu-ramuramu adọtasilẹ, on mbọ wa ṣiṣẹ na. Nigbati ilẹ ṣu ọkunrinrin na lọ ṣe gbogbo iṣẹ na ki ilẹ to mọ.

Loru ọjọ kẹta ti o ṣe akan yi tan, ni awọn ole na tun gbe mọto Jip de lati fi ko ẹru, lọ. Nwọn si ilẹkun gẹrẹbi iṣe wọn,

bi wọn ti wọle, bẹni ẹrọ kan da' un wipe. iwọ tannuni, ? Maṣe fi ọwọ kan ohun kan nibẹ yẹn, ko ṣoro yi jẹjẹ rara, aṣe lo mbu ramu-ramu, ole na tagiri.

Ẹrọ yi koiti dakẹ, ekeji dahun wipe, kai, ole! ẹ mu wọn gbogbo adugbo na wa gbojikan wipe ole! ẹ mu, ole! ẹ mu, nigbati ariwo yi pọ ni awọn ole ba ba fi mọto silẹ titi awọn fi de adugbo kejọ bẹni awọn ngbaro ole! l'ọtun l'osi. Lasigbana wa ole ko ja wọn ninu ṣọbu na mọ.

---

## Nje Ilewe Ofe Ni Eyi?

Olotu,

Ni aipe yi ni a gbo minista wa kan ti a npe ni Aja Nwachuku soro ujbikan ni ilu Eko wipe gbogbo ile iwe keke ti o wa nilu Eko nisisiyi ofe ni.

Oro yi ko ti ye wa daradara to nitoripe opolopo awon onilewe ni Yaba, Ebute-Metta ati Eko lo wipe oro yi ko je mo ti awon. Won ni Otolorin ni ile iwe ti awon Ijoba si tun fun awon ni ase lati gba owo ilewe lowo omode.

Olotu, e jowo e je ki Ogbeni Aja Nwacnuku ki o la oro na ye wa, nitoripe emi ti ri iwe eri lowo opolopo ti won gba owo ilewe lowo omo won.

Ogbeni Nwanchuku, soro na ko ye wa o.

Emi ni
Baba Egba.

---

## Sardauna ba awon Akeko soro

LONDON. Lasiko ti awọn ọmọ akẹkọ ti o mbẹ nilu Oyinbo fi ko ara wọn jọ ti awọn pe apejẹ nla kan fun awọn ti o wa ṣe eto ominira ilẹ Nigeria nilu Oyinbo nigbana ni Sardauna Sokoto, ẹni ti o nṣe Prime Minister fun ilẹ Hausa fi sọrọ yi.

Mo sọ fun awọn enia ni ilẹ Hausa wipe, awa aṣelu dabi laba-laba, bi a ba de ibi loni, a le kuro fun ẹlomiran bi o ba di ọla, ṣugbọn mo gbagbọ wipe, ijẹ nkan apa Iwọ-orun ilẹ Afrika mbẹ ni ikawọ ẹnyin ọmọ akẹkọ.

Mo fẹ ki mba nyin sọrọ diẹ nipa iṣẹ iṣelu ni ilẹ Hausa. Ohun iyanu lo ma ajẹ fun awọn ajeji ti o ba wa bẹ ilu wa wo lati ri wipe a ko ni ilọsiwaju tobẹ nilu wa nipa ẹkọ.

Ohun ti o fa sababi eyi ni wipe, o jẹ lori adehun ti awọn Baba nla temi ati awọn baba nla tiyin ti ṣe.

Nigbati awọn Gesi de Oke-Ọya, nwọn ṣe adehun pe awọn ko ni da si ọrọ ti o ba fi ara mọ Ẹsin ati aṣa ibilẹ, anfani nla gidigidi ni eyiyi jẹ fun awọn aṣiwaju wa. Ibẹru gbeji kan lọkan awọn aṣiwaju niwọn ọgọta ọdun sẹhin wipe awọn Gesi nfẹ mu ẹsin kiriyo wa si ṣiṣin wọn.

Ibẹru yi ni ko jẹki awọn aṣiwaju wa le ran ọmọ wọn lọ sile ẹkọ nigbati oyinbo gbe ṣukuru de. Nwọn ko fẹ lati ran ọmọ wọn lọ, ṣugbọn awọn ẹru ni nwọn ran silewe. Nigbati a ko ni ọmọ ti o mọ iwe jẹalẹ ni ko jẹki a fẹ lọwọ ninu iṣelu. Iṣẹ iṣelu ilẹ Hausa, lati ilu

Eko lo ti nwa, a ko ni aṣoju ninu igbimọ, ṣugbọn Ila-orun ati Iwọ-orun ni aṣoju ninu igbimọ aṣofin ilẹ Nigeria.

---



ELETI OFE
A-NIPA-WON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI-OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 22370
VOL. IX. NO. 524. LAGOS, SATURDAY JUNE 15 1957

## Ijoba Ododo Ni Yio Duro Sinsin

Nilẹ Yoruba bi enia kan yio ba jẹ oye ọba, nigbati awọn afọbajẹ ba ti ṣe gbogbo iṣẹṣe fun oluwarẹ tan, nwọn o fi Ida ati Abẹrẹ le lọwọ. Itumọ eyi ni wipe o di alaṣẹ lati pa, bakanna l'o si ni aṣẹ lati dariji.

Eniti yio ṣe Ijoba ododo ko ni bẹru ẹnikan, bẹni ko ni ṣe ojusaju enia pẹlu; ohunkohun ti o ba ti de, yio ni igboiya lati ṣe otitọ ati ododo niwaju enia ati niwaju Ọlọrun, yio si tun funimọ wipe ko si ohun kan ti enia le ṣe ni ikọkọ ti Ọlọrun Ọba Olodumare ko ni ri nitoripe gbogbo aṣiri patapata, kedere l'o ṣipaya niwaju Ọlọrun.

Nipa ṣiṣe bayi nigbana ni Ọlọrun Ọba ti o ju awọn ọba lọ, alagbara julọ yio tunbọ ma kara kun iranlọwọ oluwarẹ. Ijoba ododo ko ami ẹnikan l'ọrẹ ki o si yan ẹnikeji ni ipọṣi, yio ma tẹti si igbe ati imọran awọn enia rẹ.

Abẹtẹlẹ tabi ibolẹjẹ arun kan ti o buru gidigidi, ti o nsọ Ijoba alagbara di yẹpẹrẹ niwaju awọn enia. Ẹnyin ne ẹ gbọ bi ọrọ owe yi tiwi. "Ododo l'o ngbe orilẹ-ede leke". Ko ọlọgbọn, on yio si mọgbọn siwaju, ko ololo on yio ma pọsi ni imọ, ibẹru Ọlọrun ni ipilẹṣẹ ọgbọn.

Ijoba Ododo ni yio duro Ṣinṣin.

## Oloye Okorodudu



Eleti o bẹru ninu aworan yi ti o nwo awọn ọmọde ti a npe Ludo ni Oloye Okorodudu ati iyawo rẹ. On li ṣe ase repẹrẹ fun awọn ikọ ti o lọ gba ominira ba lati ilu oyinbo ninu ile rẹ, lati fi nkan pamọ.

Die ninu awọn ijoye enia ti o wa nibi ase na ni Oloye Awolọwọ; S. L. Akintola; Dokita Udo Udoma; S. G. Ikoku; Adegoke Adelabu, J. S. Ọlawoyin, ati Rotimi Williams.

## Itan nipa Balogun Ogundipe

Bi ọmọde ko gbọ itan yio sa gbọ arọba, nitoripe arọba yi ni baba to nilẹ itan. A gbọ lati ẹnu awọn opitan wipe, enia gbẹ lẹgẹ ni Balogun Ogundipẹ, ko nṣe enia ti ara rẹ kuku dudu, o mọra diẹ, o si gun.

Awọn opitan sọ wipe, Ogundipẹ ko gbọdọ ki enia pe "o ku" bẹni a ko gbọdọ ki i bẹ pẹlu. O ni ibẹru lara jọjọ nigboro Abẹokuta, tobẹ bi ẹnikan ba daruko Ogundipẹ ni awujọ, nṣe ni awujọ na yio tuka yanga. Nigba aiye rẹ, ko si ẹni ti o le bimọ ti yio sọmọ rẹ ni Ogundipẹ.

Ko si ọba kan nipataki ti aṣẹ ilu mbẹ ni kawọ rẹ nigba aiye Balogun Ogundipẹ. On funra rẹ lo nṣe ilu, on si ni gbogbo Abẹokuta gbikanle. O ni awọn agba nlanla ti o ngbe lọ s'oju ogun, awọn Idahomi mbẹru rẹ pẹlu.

Lọdun ti ogun Ibadan gbero pe, afori-afọrun afi bi nwọn ba ko Abẹokuta. Ajayi Ogbori-ẹfọn lo ko awọn ogun na wa. A gbọ wipe nwọn ti wa lẹnu ija na pẹ diẹ, ṣugbọn nigbati Ogundipẹ de oju ogun, awọn ara Ibadan salọ. Nigba na ni Ogundipẹ wa fi wọn korin bayi wipe:-

O gb'ogun wa ju wa o sa pada
Ogun Ajayi Ogbori-ẹfọn

Ogundipẹ jẹ ẹni ti awọn Idahomi, Egun ati Awori mbẹru gidigidi. Awọn ọmọ lẹhin Ogundipẹ a ma fi ọla baba wọn yi gbe sumọmi kakiri awọn ilẹ Awori. Awọn opitan sọ pe, Ilogbo ni orile awọn ara Ọtọ, ṣugbọn nitori ibẹru-bojo awọn ọmọ lẹhin Ogundipẹ, on lo le wọn lọ si erekuṣu Iddo.

Ohun ti o ṣẹlẹ si awọn ara Ọtta ti nwọn fi tuka si eredo ati eti ọsa, Igboro ilu Ọtta ni gbogbo wọn ti papọ si ri.

Nwọn sọ wipe Balogun Ogundipẹ ni aṣọ egbogi kan lọwọ bi o ba da bora loju ogun, ọta ibọn kan ko ni ba, awọn Idahomi, bi nwọn ti ni egbogi, nwọn ko le pa Ogundipẹ, ko si si ogun ti yio lọ ti ko ni ṣẹgun. A gbọ wipe ogoje ni awọn iyawo rẹ, ati wipe awọn ọmọ rẹ tọ bi ọmi. Balogun Ogundipẹ dagba di arugbo ati titi o fi ku, ko ye ogun ja, ọmọ Igbein ni Balogun na.

Nigba aiye rẹ, iṣẹ agbẹdẹ irin lo nṣe, ati wipe ọwọ osi lo fi nlu irin, a ma rọ ibọn, ọfa, kondo, o si tun nṣe ẹta ibọn.

## Ọjọ Ariya Awọn Jagunjagun Ni Zaria

(Lati ọwọ ỌLA ỌNATADE)

(O bẹrẹ ninu Iwe wa ọsẹ tokọja)

Gẹgẹbi mo ti sọ fun ẹnyin ọkawe wa ni ọsẹ ti o kọja wipe awọn origi enia meji ni wọn nwa lati gba sinu iṣẹ ṣọja, (jagunjagun) - ikini, awọn "Oṣlo" ọdọmọde ti wọn ṣẹṣẹ fẹ jade nilewe - ikeji, awọn agun-to-aṣọlọ. O si ni lati mọ iwe ki o si mọ kọ pẹlu. Iyẹn bẹ.

Nibikibi ti wọn ba gbe gba ọ, a ni lati mu ẹ wa si ile ẹkọ awọn jagunjagun ti a npe ni Nigerian Regimental Training Centre nilu Saria.

Boya orukọ ilu yi, Saria - "Sare-ko-riya" le fẹ ba ọ ni ẹru. Awọn babalogun to wa nibẹ sọ wipe awọn ko nfi iya jẹ enia, ṣugbọn oṣu meji gbako ti wa ṣe nibẹ, iwọ na a mọ wipe o kọ ẹkọ gidi ti o nsọ ọmọkunrin di odun.

Ti o ba di ifamọra rẹ ni owurọ, ti o gbe ibọn rẹ ti o nkọ in:

"Baba nre Mẹkka
Iya nre Medina
Girigi nmasa".

O ni lati tun pada wa si ije iwe pẹlu nkan ikọwe rẹ ki o si ma wi tẹle olukọ rẹ bayi;

(Wo yoku loju ewe karun)

# Ẹsin Iya Oba Sorire



Ẹnti a nwo yi ni Iya ọba Obinrin Elizabeth Keji ti o nṣe ọba ilu oyinbo. O wa ninu awọn enia ti o lọ woran ẹṣin ọba ti a npe ni Doutelle nibiti o gbe nsare ije, Ẹsin ti a wiyi lo gba ipo keji ninu ere na. Ẹṣin ọba keji a ti npe ni Pipe of Peace to gba ipo kẹta.

## Ojo Ariya awon Jangunjagun

(Obẹrẹ loju ewe kẹrin)

'Mo ri ọ-iwọ na nwo mi'. Gbogbo rẹ ni ede Gẹsi ni o.

Awọn ọga ṣọja ni o fẹ, o kẹ, o nilati gbọ oyinbo tipatipa ni ọdọ awọn. Wọn si gba awọn oluko bi rẹrẹ ti yio kọ ẹ si irinwo ede Gẹsi (400 English words) ki o to jod kuro nibẹ bi ṣọja.

Gbedegbẹyọ Gẹsi nikan kọ ni o ni lati mọ o, o ni lati mọ itan, nipa iṣiro owo ati ẹkọ nipa aiye.

Bi o ba tan 'ẹ alakinkọnja, ẹmọkunrin ti o fẹ kọ ẹkọ siwaju si, o ni lati ma gba iwe ẹkọ-okere (correspondence) lati ilu oyinbo, awọn ọga jagunjagun ni awọn ti ṣe tan lati ma ba ẹ ṣun'wo rẹ

Ki a to tu kuro nibẹ ẹkọ, awọn Tiṣa, olukọni ti awọn jagunjagun wọnyi gbọ ko se fi ọwọ rọ kuro ninu eto ẹkọ. Wọn mọ iṣẹ wọn niṣẹ gid. Nigbati emi alara papa de ibiti a nkọ wọn ni ẹkọ ni Zaria, o dabi ẹnipe kin ntun pada di ọmọ ilewe.

(Wo yoku loju ewe keji)

# Olomolanke ti ko bikita atilowo moto ti ko ni suru.

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT DRIVER




Ijọba ti ṣe ofin wipe, nitori ki o ma ba si gbọn-gbọn, k awọn eniti o nlọ, moto, kẹkẹ ọmọlanke ati awọn enia, ki nwọn ma pọ si apa osi; bẹni ki awọn ti o mbọ ma po si apa osi, nigbana ko ni si jamba to bi iba ti po to.

1 Ṣugbọn, ẹ wo Ọlọmọlanke ti o nlọ yi, ko pa ofin yi mọ, ọwọ ọtun lo ngba lọ, gbogbo awọn enia ti o duro lọtun-losi rẹ lo nk'egbe wipe Ha! ọlọmọlanke yi o ṣi ọna gba. Kaka ki o gbọ, o ṣa nfi ori kunkun fa kẹkẹ rẹ lọ.

2 Onimọto kan lo yọ lokere; ti o nfan fere lọwọ yi, kaka ki Ọlọmọlanke yi duro tabi ki o ya kuro lọna, nṣe lo sa ntẹ siwaju; gbogbo awọn enia si nke ibosi rẹ; Onimọto ẹwẹ, ko ni suru ki o jẹki o kọja lọ, ṣe lo kuku sọlu ọmọlanke, ọkunrin oni basikulu ti o mbọ lẹhin ko tete ṣakiyesi ewu ti o mbọ niwaju yi on na tun sọlu ọmọlanke, o si daku si oju ọna moto.

3 Oni moto na si ba tirẹ lọ, Ọlọmọlanke salọ; ẹru danu; Oni kẹkẹ ku; ẹ tilẹ wo bi nwọn ti ba oju Titi jẹ.

Ẹnyin enia; ẹ ma rin si apa osi nibikibi ti ẹ ba nlọ larin ilu Eko.



### ẸGBẸ SCOUT PỌ LODE AIYE

Nsgbati awọn ọjọgbọn gbaiṣiro le gbogbo awọn ọmọ ti o jẹ Scouts ati Guides kakiri agbaiye, ni iye awọn ti o mbẹ labẹ ede Gẹsi nikan to adọjọ ọkẹ enia (3,000,000).

A gbọ irohin wipe, awọn ẹgbẹ Church Missionary Society ṣe otitẹ gbogbo ede ti o mbẹ ni orilẹ Afrika sinu iwe mimọ Bibeli, a si gbọ wipe, iye bibeli ti awọn ta si lọ Larubawa ni iha ariwa ilẹ Africa nikan to ọkẹ mẹta ko si ti ilẹ Nigeria nibẹ.

OJU EWE

# awon meta.

Lati owo
Ade Buraimoh

Awon ore meta kan wa lati kekere, oruko awon omo na ni wonyi Suru, Suru-lojo, ati Suru-baba-iwa. Nigbati won bere si se ore won yi bo lati kekere titi won fi di agbalagba.

Nigbati won wa d'agba tan, won wa mo pe bi ako ba se ise aki ini owo lowo, lati fi se enia rere, nigbana ni awon omo yi wa lo fi ise oko bale, ni eba Ilu won. Nigbana won to omo odun mewa mewa. won wa ko ahere si oko won na, nigbana won bere si ro-oko won si tun gbin ohun ogbin lorisirisi bi Ila, Agbado, Isu Owu, Gbaguda; Ata; Alubosa-Elewe ati orisirisi nkan miran pelu si oko won; awon ohun ogbin yi wa hu jade; ti won si ndagba s'oke.

Nigbati agbado wa nyo omo jade; oko ti Suru ko yo omo jade bi ti awon to ku re; nigbati isu to asiko lati ma ta; ti Suru-lojo ko ta jade bi ti awon toku re; nigbati Owu ti Suru-baba-iwa ko yo jade bi ti awon toku re bakanna.

Gbogbo won dari yo si ahere won; onikaluku won wa nso nkan to sdun lokan; nipati ohun ogbin won ti ko dara; Suru wa dide; o ni agbado ti on ko dara ni odun ni; ko daju pe emi ko ni kuro ni ibi yi; tabi ki on wa ise miran se; to je wipe ise na ise na yio yato si ti agbe.

Suru-lojo wa fi enu le tire na; isu ti on ko ta ni odun ni; ko da ju pe mi o ni kuro nibi ise agbe ni odun ni. Nigbana ni o wa kan Suru-baba-iwa; ohun ti o koko wi nipe; ha! oju ti mi; aso ibora mi gbo tan yanyan ni odun ni; mo simi bi Owu mi ba yo dada; emi yio ni aso ibora ni odun ni, kini no ti wa se oro yi si o; enyin ore mi?

Suru tun dide; oni emaje kia banu jo rara ire egbe wa wa tio ntoro je; kini yio wa fa ti ao fi kuro ni oko wa nibi yi; Olorun maje kia toro je o; gbogbo won se Amin.

Lehinna ni Surulojo dide, akoko oro mi nipe, ako ti wo odo Oni (Crocodile) nfawa lese eyi mi rara o enyin ara mi oye kia ronu pi wada kia si mo ohun ti ao mu owo wa le lori tori ojo kodu-ro de eni kankan ninu wa.

Suru-baba-iwa tun wa dide, kini kan ni awa yio se nisisiyi, nkanna, emi ko mo, beni enyin na kosi mo bakanna ayafi bi aba ro ori wa jinle, ao to mo ohun ti awa yio se bokan je odun to nbo ni atoro oro na tan, kia ma fa gun won gba oro Suru nibaba-iwa.

Nigbati Onikaluku won wa mu ohun ogbin won lo ta ni oja, lehin igbati won ti yo eyiti won yio tun gbin sile, ati eyi ti won yio maje pelu, enikokan won wa ri owo Ponun mewa (£10 each) kia ma fa oro na gun lo titi, won ta ohun ogbin won tan ibanuje tun wa po ju ti ehin wa lo. (Olorun ma fi iru re si waju wa. Ninu ise ti a nse Amin).

(Wo yoku loju ewe keje)

No 80

# Federal Medical Services

## Vacancies For Student Nurses Or Midwives

Applications are invited from Girls with General Schools Certificates, Middle IV, Secondary Class III and IV Certificate or Modern II Certificate for training as Nurses or Midwives. Preference will be give to candidates of School Certificate standard.

2. Those who are accepted will enter the Nurses Preliminary Training School, Lagos for a 6 months course which will commence in October, 1957. During this course students will be required to reside in a Government Hostel or in an approved lodging house. A subsistence allowance at the rate of £7 a month will be payable and where maintanance is provided a charge of appromimately £4 a month will made.

3. On completion of this Preliminary Course, successful students will be appointed as Probationer Nurse or Pupil Midwives in the salary scale N.I. which commences at £150 a year. They will be posted either to the General Hospital, Lagos, for training in General Nursing or to the Massey Street Maternity Hospital, Lagos for training in Midwifery.

4. Candidates are required to forward the following documents with their applications which should reach the PRINCIPAL MATRON, FEDERAL MEDICAL HEADQUARTERS, LAGOS, on or before the 31st July, 1957.

(i) Copy of the Certificate of Education.
(ii) Copy of Birth Certificate or of a Sworn Declaration of Age made by parent or guardian.
(iii) Copies of 3 recent testimonials, one of which should be from the Headmaster of the last school attended or from the most recent employer.

5. Only those candidates who are selected for interview will receive a reply.

# Itan Lagelu

Awon Opitan so wipe, nigbati Lagelu mbo lati Fiditi, ti o de arin awon oke ti o mbe ni Eleyele, o ngboro ilu, o gbo ariwo opo awon enia. Oria ti nwon si nko lojo na fere jo orin bayi pe:-
Olowo ireke, ododun nireke nso.

ISOKAN ILE NIGERIA NI A FE



Gbogbo enia lo kigbe wipe isokan ile Nigeria ni nwon fe. Lati ti nan wipe isokan ti o mbe lokan awon asiwaju wa. A ko lero wipe lati gba ti a ti njijakadi fun ominira ile Nigeria, ohun kan wa ti o le pa Oloye Awolowo po pelu awon Hausa bayi ri.

Ninu aworan oke yi, nigbati ero isokan ile Nigeria wa ni okan awon asiwaju wa, eo ri irepo larin awon Hausa ati Yoruba bi o ti po to.

Awon ti o duro ninu aworan yi lati owo otun, ni Oloye Rotimi Williams, Oloye Obafemi Awolowo, Alhadji Ahmadu, Sardauna Sokoto, Oloye C, D, Akran ati Muhamad Ribadu

# Ojo Ariya Awon Jagunjagun Ni Zaria

(Obere loju ewe karun)

OFE NI TOMO RE

Irobin ko to afoju ba ni ilewe jagunjagun ti o tun wa ni Kaduna. Bi o ba bi omo, ti o si nse ise soja, lofe ni omo re yio gba eko titi de inu iwe oyinbo keta (standard III). Lati ibere titi de opin ede Oyel ni won fi ako won.

Se fun mi, bawo ni ko se ni mo iwe pelu tipatipa ? Bi o ba tun di oga die ninu ise ti nwon gbe e lo si Ibadan tabi Enugu wa tun ba eto eko re ati ti omo re bakanna nibe. Akiyesi :- Ni ose ti o mbo, Iriju wa, Ogbeni Onatade, yio so bi won ti se nse enia di jagunjagun larin osu meje ni ilu Zaria

Olotu

# Itan awon Ore meta

(O bere loju ewe kafa)

Lehinna ni won pe si ahere gegebi ti ijosi; bi Suru ti di de o si so jade lenu pe kini oruko on ti nje; w o n si dalohun pe Suru, o nba oro re l o ; eje ki a ni suru titi odun de nbo y i . Surulojo n i ko sise kosi si aise; emi yio kuro nibiyi emi y i o si mafi owo mi se owo. Surubabawa si di de o f i esi le oro ti won so p e ki awon se, o n i koburu na, ki a pa owo po; kia si le si Ilu miran nigba yen won to omo odun medogun (15 years of age) kia ma fa gun won fi ona pon, bi won ti nlo kope pupo won d e Ilu, won p a d e Ogbeni kan ti a npe oruko re ni Sonidolola; won ki bo ti to ati boti ye; gege bi alejo ti nmanki Oni Ile.

Ogbeni Sonidolola b a mu won wo inu Ile l o, o si fi jije mimu te won lorun; ki a ma gun; won bere Owo ni Ilu yi; gbo-owo tio ba won de Ilu na je adota ponun £50 won nse owo yi titi osu mefa (6 months) won wa ka oja won ni gba y e a gbogbo owo w o n wa je ogorin ponun (£80 0s 0d) titi osu mefa miran tun de; won tun siro owo won o tun je Ogorun ponun (£100 : 0s : 0d) won wa ni awon yio pada si Ilu won gba yi, gbogbo won si panu po pe koburu na, won ba se enie dani ki won to kuro ni odo Ogbeni Sonidolola, kia ma fa gun won kuro ni Ilu yi.

Nigbati yio wa se, won de ona won tan, won wa fe jeun ko wa si omi fun won lati mu rara nigbana ni won ni ki Suru lo si odo lo bu omi wa fun awon ki awon wa jeun bi suru ti kuro ni odo awon to ku re o wa nro bi owo yi yio ti se je ti ca nikan soso beni awon to uu na nro bi owo na yio ti se je ti a w o n na.

Surulojo ati Suru-babawa ti pon ada sile won ni bio ba ti de ni awon yio he lori ti owo na yio fi je ti awon nikansoso, Suru papa fun ara re na ti mura tan bi owo na yio tise je ti on na ni o ba bu ogun sinu omi ti o lo pon wa fun won lati mu, bi awon ba si ti mu omi yi awon mejeji yio siku owo na yio wa je ti on nikan.

Ko 'si ma wipe awon tohun na ti pon ada sile fun on. Awon na ko si mo pe o ti da ogun sinu omi fun awon. Ki a ma fa oro na gun Won ko ma wipe bio tiwa ni liki be ni o wa ni gbanja gegebi owe ile wa. Bio ti de ni won ba so ada si loran e si ku, beni won nyope owo yi di ti awon nikan bi won ti jeun tan, ti won nmu omi lowo beni okan ninu won baku laipe pupo ekeji na si ku pelu.

Bi gbogbo won ti se pa ara won nitori ti owo yi ko fi je ti eni kankan ninu won. Enyin okawe wa aladun oloyin momo yi itan yi ko wa pe aini fe si ara won lojo ki o w o yi je ti elomiran ti ko mabi owo ti se de.

Abe mi ree, O l o t u modupe aye ti e gba mi.

# Adelabu d'ore Awolowo



OGBENI ADEGOKE ADELABU



Awon Yoruba n'powe wipe, "bi ola yio ti ri, lati oni ni ao ti mo". Awon asiwaju wa fi nhan wa wipe agbajo owo ni a fi aso aiya, awon nfe ki Ijoba ile Nigeria je okan, ninu emi isokan na ni nwon wa ki awon to fi orile ona ibiti nwon nlo gba ominira bo wa.

Nigbati nwon si de ohun, emi isoKan ni awon fi mba ara won lo. Enikeni mo wipe Awolowo ati Adelabu, nse konrangbon si ara won ki nwon to lo silu Oyinbo. Sugbon nigbati nwon de ohun, awon mejeji di ore, tobe ti awon mejeji fi wo moto papo ti nwon si nje faaji kakiri ilu Oyinbo.

Awon ti a nwo ninu aworan yi ni apa otun Oloye Awolowo ati l'apa osi ni Adegoke Adelabu.


No. 81.

## Vacancies For Assitant Industrial Officers

Applications are invited for the posts of Assistant Industrial Officers and Assistant Industrial Officers-in-Training in the Federal Department of Commerce and Industries.

Particulars in Government Notice No. 984 in the Federation of Nigeria Official Gazette of 30th May.

Application to the Director, Federal Department of Commerce and Industries, Lagos.

Closing date15th July.


## Awon Onisowo Se Bebe Nilu Oyinbo

Awon egbe Onisowo awon ohun osbin ti o nbi ile Nigeria wa se ase repete fun awon Iko to lo silu Oyinbo laipe yi, ninu awon ti o lo sibe ni Oloye Awolowo, Sardauna ati Azikiwe.

## Awure Bamwo

Ọmọ t'a fi Bamwo tọ k i gbona, Ọmọ t'o mu Bamwo ki yokunrun, ṣakaṣaka lara wọn nle.




Bi nwọn ba ṣ'erepa l'ọsan, nwọn a sun fọnfọn l'oru. Awọn l'owere ji t'on t'ẹrin, ndaji jẹun bi ẹmọ. Oti li a da f'abiyamọ kendere pe ki o rubọ abiku, ki o ma wa Bamwo ra kiri.

Nje iku si Bamwo mọ, Ṣinimọ-ṣinimọ, arun si Bamwo mọ Ṣinimọ - ṣinimọ. " Wa ra Bamwo f u n ọmọ rẹ lọdọ wa. Igo kekere 2/6d Igo nla 4/- Owo ọkọ 1/6d fun igo kan.

**Egba Trading Aradan Stores**
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.


## Oloye Anthony Enahoro



...oikẹni ti o ba de ilu Ibadan ri, yio ri wipe iyatọ mbẹ larin awọn Ọ l ọ p a ti o ti wa ri pẹ l u awọn ti o mbẹ nisisiyi. E yiyi jẹ asyan iṣẹ Oloye Anthony Enahoro ti o nṣe (Minister of Home Affairs).

Iyatọ ti o wa na n i wipe awọn ọ l ọ p a ibilẹ latijọ a ma de fila Idara dudu, ṣugbọn a w ọ n ti isisiyi, ko si iyatọ l a r i n wọn ati awọn ti o mbẹ ni Police Training College. Dipo fila Idara dudu ( Fez Cap ) fila Tamoṣanta dudu ( Black Berrett Cap ) ni nwọn nde. E yi wu wa o. Toni, ọwọ nyin a ran o.

## I j o b a K o F e Rifofa (Revolver) Lowo Enikan Mo

EKO. Niwọn igbati o jẹ wipe, edekoyede ti bẹ silẹ larin awọn Ijọba nipa awọn enia ti o laṣẹ lati ni iwe fun lilo ibọn Rifọfa a t i ibọn ilewọ, nigbana ni aṣẹ yi jade

Ohun t i o w a n i b ẹ n i wipe, Ijọba yio tunbọ mu ogiri siwaju nipa fifunni ni iwe aṣẹ lati ma lo ibọn Rifọfa ju ti atẹhin wa lọ eniti I j ọ b a b a s i r i wipe, ko tun ni ẹtọ mọ lati ni iru ibọn ti a wi yi lọwọ, ni arin ilu Eko, aṣoju Ijọba yio kọwe si oluwa rẹ wipe ki o wa fi ibọn na le Ijọba lọwọ ni Kotu Oke-Suna ki ọjọ meje to pe.

Ijọba yio tọju ibọn na fun ọdun kan abọ, lẹhin eyi ẹniti o ni ibọn na le gbe ta fun ẹlomiran ti o ni iwe aṣẹ rẹ lọwọ tabi ki o ṣe e bakan, bibẹkọ, Ijọba yio fi ofin le.

## Rogbodiyan Tun Be Ni Nikosia

NIKOSIA - Ni e r e k u ṣ u Nikoṣia, n i b i t i ijọgbọn nsaba ma bẹ silẹ nigba gbogbo. Ijọba Gẹsi Kede isẹde; n i t o r i k i a l a f i a le wa.

Sibẹsibẹ. ijagboro t u n bẹ silẹ larin a w ọ n ara ilu na ati awọn Ọlọpa. Ohun t i a s i gbọ p e o da ija na silẹ ni wipe, lakoko ti rogbodiyan ijagboro ṣi gbojikan ni ilu na, larin Ijọba ati awọn ara ilu, aṣiwaju awọn janduku ti o mba ijọba fi ori gbaori, ti nwọn npe ni Gregoris Afxentiou ku ninu ija na.


## The National Bank of Nigeria Limited

### Ileya Shilling Fund - June 1957

Depositors in the Ileya Shilling Fund are hereby reminded that, in accordance with the regulations governing the Fund, they may withdraw their deposits as from Monday, June 17, 1957.

Withdrawals can only be made by depositor in person and on production of his passbook. In case of distant depositors, early application for a withdrawal form should be made to the Manager of the Branch concerned, such application to be accompanied by the depositors passbook, for interest to be entered up.

Withdrawals for the year will close on July 13, 1957 and depositors who fail to withdraw on that day cannot do so until next Ileya.

Payment shall be made in the following alphabetical order of the Depositors' surnames on the date shown hereunder and contributors who fail to apply on the prescribed date shall not be attended to until Monday June 24, 1957.

| | | |
|---|---|---|
| A to B | Monday | 17th |
| C to H | Tuesday | 18th |
| I to N | Wednesday | 19th |
| O to R | Thursday | 20th |
| S to Z | Friday | 21st |
| A & O | Saturday | 22nd |

For the year 1958 deposits will be taken as from Monday, July 15, 1957.

BY ORDER OF THE GENERAL MANAGER.



Bi ehin tabi igba aiya ba ndun o ? fi egbogi Ajebidan yi wo ibe.

